**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**DÍDÒJÚKỌ ÀWỌN Ẹ̀MÍ ÒKÙNKÙN ÀJÀKÁLẸ̀-ÀRÙN TÓKÁRÍ AYÉ (2)**
**OṢÙ KẸRIN 2022**
Ìwé Mímọ́ kíkà: Orin Dáfídì 17; 27; 91
Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Mo dábóbò ayé mi kúrò lọ́wọ́ gbogbo àyalù àwọn ọmọ àjèjì àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, ní orúkọ Jésù.
6. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, jó gbogbo irúgbìn àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí kúrò nínú àgọ́ ara mi, ní orúkọ Jésù.
7. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, dábóbò ayé mi kúrò lọ́wọ́ gbogbo ẹ̀mí àjàkálẹ̀-àrùn, ní orúkọ Jésù.
8. Mo palẹ̀nú mọ ohùn àwọn ọmọ àjèjì àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, tó n ṣọ̀rọ̀ lòdì sí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
9. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, fún mi ní àbò àjẹsára lòdì sí gbogbo àìlera tó n jẹyọ láti ipasẹ̀ àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, ní orúkọ Jésù.
10. Àgọ́ ara mi, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, kọ gbogbo àìlera, ní orúkọ Jésù.
11. Èmi kì yóò kú bíkòṣe yíyè, kí n lè ma ròyìn iṣẹ́ Olúwa ní àkokò yî, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo ọfà àjèjì àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé tí wọ́n ta sími, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
13. Ìwọ agbára afiniṣòfò tóti ipasẹ̀ àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí jẹyọ, àgọ́ ara mi kì í ṣe èrò rẹ, ká kúrò, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo àtẹ̀gùn òkùnkùn, tó n kí àwọn ìránṣẹ́ òkùnkùn káábọ̀ sínú àgọ́ ara mi, fọ́ dánù, ní orúkọ Jésù.
15. Mo gba ògùn ẹ̀jẹ̀ àti ajíra atokèwá nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.

**16.**Ẹ̀yà ara mi, gba iná ọ̀tun, kí o sì di ohun tí aìlèra-kí-aìlèra kòlè pèníjà, ní orúkọ Jésù.
**17.**Gbogbo àjàgà àti májẹ̀mú tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí ṣokùnfà rẹ, ayé mi kì íṣe èrò rẹ, fọ́, ní orúkọ Jésù.
**18.**Gbogbo ètò ẹ̀mí ikú fún àgọ́ ara mi, tóti ipasẹ̀ àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí jẹyọ, kú dánù, ní orúkọ Jésù.
**19.**Mo sọ̀rọ̀ ègbé sí gbogbo olùyọ ayànmọ́ mi lẹ́nu, ní orúkọ Jésù.
**20.**Mo lé gbogbo ìmísí òdì àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí kúrò nínú àgọ́ ara mi, ní orúkọ Jésù.
**21.**Gbogbo ìdákọ̀ró àwọn afiniṣòfò, àgọ́ ara mi kì íṣe èrò rẹ, dópin, ní orúkọ Jésù.
**22.**Ẹ̀mí Mímọ́ àti agbára òjìjì Olódùmarè, ṣíji bòmí, ní orúkọ Jésù.
**23.**Ọlọ́run, dìde, jẹ́ kí àgọ́ ara mi gbóná jù fún gbogbo ẹ̀mí òkùnkùn aìsàn, ní orúkọ Jésù.
**24.**Gbogbo aìsàn dójú ikú, tóti ipasẹ̀ àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí jẹyọ, èmi kì íṣe èrò rẹ, kú, ní orúkọ Jésù.
**25.**Àgọ́ ara mi, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, dí kò ṣeé jẹ́ fún àwọn jẹran-jẹran àti mùjẹ̀-mùjẹ̀, ní orúkọ Jésù.
**26.**Àjẹsára àtòkèwá, gbé mi wọ̀, kí o sì kún mi, ní orúkọ Jésù.
**27.**Gbogbo iṣòro tí àwọn ọmọ àjèjì àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí ṣètò lòdì sí ayé mi, di asán, ní orúkọ Jésù.
**28.**Gbogbo àsọtẹ́lẹ̀ òkùnkùn, àdúrà òkùnkùn, ìfẹ́ òkùnkùn lòdì sí àlàfíà mi, túká, ní orúkọ Jésù.
**29.**Gbogbo ejò àti àkéèkè ti ẹ̀mí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, mo rún ọ wómú-wómú, ní orúkọ Jésù.
**30.**Ẹ̀jẹ̀ Jésù, Iná Ẹ̀mí Mímọ́, fọ ara, ọkàn àti ẹ̀mí mí mọ́, ní orúkọ Jésù.
**31.**Gbogbo agbára tí wọ́n yàn kó dàmú ayànmọ́ mi láti jẹ́ kí n fìdírẹmi, kùnà, ní orúkọ Jésù.
**32.**Agbára Ọlọ́run, ṣíji bo gbogbo ẹ̀yà ayé mi fún iwòsàn àti ìtúsílẹ̀ pátápátá, ní orúkọ Jésù.
**33.**Gbogbo àjàgà àínítúra, ìdárungún àti ìbíntín tí àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí ṣètò lòdì sí ayé mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
**34.**Ẹ̀yin ángẹ́lì ogun,níbo lẹ wà, ẹ dìde, kí ẹ sì jà fún mi ní àkokò yìí, ní orúkọ Jésù.
**35.**Ẹni ẹ̀mí mi, kún fún iná Ẹ̀mí Mímọ́, kí o sì kọ gbogbo ọfà òkùnkùn, ní orúkọ Jésù.
**36.**Gbogbo ohun rere tímo pàdánù ní àkokò àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, mo gbà wọ́n padà, ní orúkọ Jésù.

**37.** Gbogbo àkọsílẹ̀ àwọn ìkà, tí wọ́n kọ ní àkokò àjàkálẹ̀-àrùn tókárí ayé yìí, kí ẹ̀jẹ̀ Jésù pawọ́n rẹ́, ní orúkọ Jésù.

**38.** Ẹ̀mí Mímọ́ àti Iná, kún ara, ọkàn àti ẹ̀mí mi, ní orúkọ Jésù.

**39.** Gbogbo ohùn búburú, tó n sọ̀rọ̀ lòdì sí ẹ̀jẹ̀ mi, mo pa ọ́ lẹ́nu mọ́, ní orúkọ Jésù.

**40.** Ọwọ́kọ́wọ́ tó fẹ́ gbẹ̀san lòdì sími nítorí àwọn àdúrà mi, gbẹ nípa iná, ní orúkọ Jésù.